## (113) Suratul - Falaki

سُورَةُ الفَلَقِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye,*
*Aṣakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Sọpe: Mo sadi Oluwa owurọ̀ kùtùkùtù (Falaki).

قُلۡ أَعُوذُ بِرَبِّ ٱلۡفَلَقِ ١

**2.** Kuro nibi buburu ohun ti O da.

مِن شَرِّ مَا خَلَقَ ٢

**3.** Ati kuro nibi buburu ti òru nigbati o ba ṣú biribiri.

وَمِن شَرِّ غَاسِقٍ إِذَا وَقَبَ ٣

**4.** Ati kuro nibi buburu awọn opidan ti nwọn mã npọfọ sinu koko (ti nwọn tá).

وَمِن شَرِّ ٱلنَّفَّٰثَٰتِ فِي ٱلۡعُقَدِ ٤

**5.** Ati kuro nibi buburu onilara nigbati o ba nṣe ilara.

وَمِن شَرِّ حَاسِدٍ إِذَا حَسَدَ ٥

## (114) Suratul -Nãsi

سُورَةُ النَّاسِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye,*
*Aṣakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Sọpe: Mo sadi Oluwa awọn enia (Nãsi):

قُلۡ أَعُوذُ بِرَبِّ ٱلنَّاسِ ١

**2.** Ọba awọn enia.

مَلِكِ ٱلنَّاسِ ٢

**3.** Ọlọhun awọn enia.

إِلَٰهِ ٱلنَّاسِ ٣

**4.** Kuro ni ibi aburu esu oni royiroyi ti o si ma nsa sẹhin (ti enia ba darukọ Ọlọhun).

مِن شَرِّ ٱلۡوَسۡوَاسِ ٱلۡخَنَّاسِ ٤

**5.** Ẹniti o nsọ royiroyi sinu igbaiya awọn enia.

ٱلَّذِي يُوَسۡوِسُ فِي صُدُورِ ٱلنَّاسِ ٥

**6.** Lãrin awọn alijọnu ati awọn enia.

مِنَ ٱلۡجِنَّةِ وَٱلنَّاسِ ٦